OWE
Akuku i jẹ oye o sin ju ẹnu mi ko ka ilu lọ.

# Irohin Yoruba

Vol. IX. No. 446. MONDAY, JANUARY 25, 1954. KOBO KAN (1d.)

E MA A POLOWO
Oja Nyin Sinu
Iwe Irohin Yoruba

# IPADE IGBIMO ATUNSE OFIN ISELU NIGERIA BERE



Ọlọla LYTTELTON
(Alaga Igbimọ Aṣofin)

EKO.—Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni Ipade Igbimọ Atunṣe Ofin ilu Nigeria bẹrẹ ninu Ile Apapọ Igbimọ-Nla Aṣofin Nigeria l'Eko.

Ohun ti o fa a ti ko fi bẹrẹ ni ọjọ Aje gẹgẹbi ọjọ ti nwọn ti pinnu lati bẹrẹ nipe Ọlọla Oliver Lyttelton Alamojuto Ilu amọna Ijọba Gẹẹsi ti yio ṣe alaga ipade na ko tete de, Ọkọ Ofurufu ti o wọ fi ọjọ kan pẹ ki o to de s'Eko, ni ọjọ Aiku (17/1/54) ni o to de, Gomina ati gbogbo awọn Olori Ẹgbẹ Oṣelu Nigeria ni o si lọ pade rẹ ati awọn ẹmẹwa rẹ ti o ba de ni Ebute Ọkọ-Ofurufu Ikẹja.

Nigbati nwọn si bẹrẹ ipade na gbogbo awọn asoju Ẹgbẹ Oṣelu igun mẹtẹta Nigeria ni o pe si ibẹ. Ọlọla Lyttelton ti o ṣe Alaga Ipade na si sọ ọrọ alaye lori ohun ti nwọn fẹ ṣe ni ipade na.

Gbogbo awọn Olori Ẹgbẹ Oṣelu na, Sardauna Ṣokoto (N. P. C.], Dọkita Nnamdi Azikiwe [NCNC] Prof. Eyo Ita N. I. P.) Malam Aminu Kano [N. E. P. U.) Dọkita Endeley [K. N. C.) si ki Ọgbẹni Lyttelton ku abọ pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ ti o ba de, awọn ti o si sọrọ fi alaye diẹdiẹ kun un nipa ero wọn fun atunṣe ipade na.

Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ (Action Group] ko sọrọ ṣugbọn o ṣe alaye pe ohun ti ko jẹki on sọrọ ni ọjọ ibẹrẹ ipade yi ni pe ọrọ ti awọn Ẹgbẹ Action Group mu wa si ipade yi lori eto owo pinpin fun inawo ilu kọkan ti pọ pupọ ṣugbọn Ọba Ọni Ifẹ ni ẹniti o sọrọ dipo Olori Ẹgbẹ Action Group, o si ki Ọgbẹni Lyttelton ku abọ loruko Igbimọ-Ijoye ati Igbimọ Aṣoju Ijọba Iwọ-orun Nigeria.

Nigbati Ọgbẹni Lyttelton, Alaga ipade na o fi pari ipade akọkọ-bẹrẹ ni ọjọ na ni o yọ siga-murada kan o si fi han gbogbo ipade na pe alẹ ọjọ ti o ku ọla ti on o kuro ni ile lati ma bọ wa fun Ipade Igbimọ yi ni Ọlọla Churchill ti iṣe Alakoso [Prime Minister] Ijọba Gẹẹsi fun on ni siga-murada na fun apẹrẹ aṣeyọri rere Ipade Igbimọ yi, ati pe ti nwọn ba ri i ti on ba fi ina si siga na ti on ba ng mu u ki nwọn mọ pe "Inira gbọn'mi si i-omi-oto, gba-were-nko-gba-were ti a fi gb'ariwo ọja wọ inu ajọ Igbimọ ipade yi niyẹn" o ni on si ni igbẹkẹle pe ipade Igbimọ na ko ni daru de aye pe ki on fi mu siga na.

Ni ọjọ keji ti nwọn bẹrẹ ipade na ni awọn aṣoju Ẹgbẹ Action Group mu Iwe-Eto ti nwọn ti kọ ti nwọn si ti to lẹsẹsẹ bi o ti tọ ki nwọn pin owo-ina ilu Nigeria si ti ko fi ni i ni pe irẹjẹ wa nibẹ, Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ si sọrọ fun wakati meji lori alaye yi. Bi nwọn ba ti pari ipade na si ẹ o ma a gbọ.



Aworan yi ni ti awọn ijoko Aṣoju Ẹgbẹ Action Group ninu Ipade Igbimọ Atunṣe eto iṣelu Nigeria. Ijoko wọn lati ọwọ osi:- Oloye Arthur Prest, Ọlọla S. L. Akintọla, Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ Ọba Alaiyeluwa Aderẹmi Kini, Ọni Ifẹ, Ọgbẹni Ayọ Roṣiji, awọn ti o joko lẹhin ni:- Ọba Alaiyeluwa Ọlọwọ Ọwọ, Ọgbẹni Alfred Rewane, Ọlọla Iyaafin Rẹmi Aiyedun Ọgbẹni S. O. Shonibarẹ ati Obi Idumuyo awọn ti o wa lẹhin patapata ni:- Ọgbẹni S. O. Awokọya, Tony Enahoro ati Ọgbẹni G. C. Nonyelu.

## Isin Iranti Bode Thomas

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi ni awọn Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa ati Ẹgbẹ Action Group ṣe Isin Iranti fun Oloye Bọde Thomas Balogun Ọyọ. (Ẹniti o jalaisi ni ọjọ Eti ti iṣe ogunjọ oṣu kọkanla ọdun 1953) ninu ile Isin Ọlọrun Ijọ African Cathedral (Bethel).

Isin Iranti na bẹrẹ ni deede Agogo mẹta ọsan, ki isin na to bẹrẹ ni ẹsẹ gbogbo awọn Oloye Ẹgbẹ mejeji na ti pe ṣoṣọ sibẹ pẹlu awọn Ijoye ilu gbogbo ati awọn Ọlọla lati igun mẹrẹrin ilu Nigeria, awọn enia ti o wa si ibi isin na to ẹgbaa (2000) enia.

Lẹhin ti nwọn to wọ inu Ṣọọṣi tan pẹlu orin-aro, Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ ni o ka ẹkọ pataki ti a yan fun Isin Iranti na, Ẹni-ọwọ Biṣọpu A. Abọyade-Cole ni o ṣe akanṣe Iwasu ọjọ na, o si sọ ọrọ iwuri pupọ nipa igbesi aiye Ologbe Ọlọla Akanbi Ọlabọde Thomas. Bi o ti fi gbogbo agbara rẹ sin ilu rẹ ti ko si fi iṣẹ isin rẹ si Ọlọrun jafara titi de oju iku. Lẹhin Iwasu, awọn Akọrin Ijọ kọ orin-aro ni iranti Ọlọla Bọde Thomas. Nwọn si gba adura, nwọn si kọ orin akọjade.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn enia ti o wa si ibi Isin Iranti na ni awọn Iriju Igbimọ Ijọba Iwọ-orun Nigeria ati ti Apapọ Igbimọ-Nla Nigeria, ti nwọn jẹ ọmọ Ẹgbẹ Action Group, Oloye Onikoyi Eko, Ọmọ-Ọba Adeleke Adedoyin, Ẹni-ọwọ Biṣọpu A. W. Howells, Ọgbẹni E. E. Esua, Onidajọ-Kekere A. Abayomi, Ọba Ewusi Makun, Aṣoju Alafin Ọyọ ati awọn Aṣoju Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ọyọ.

REDIFFUSION
FOR LESS THAN THREEPENCE PER DAY
you can obtain
NEWS
MUSIC
EDUCATION
ENTERTAINMENT
FROM 6 A.M. to 11 P.M.
IN YOUR OWN HOME
APPLY AT OFFICES IN LAGOS, IBADAN & ILESHA.

# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## Idahun si ibere Alfa J. S. Animashaun - Ilesha

OLOTU, mo ki yin pupọ. Ẹku iṣẹ laada. Ọlọrun Ọba ko fi iṣẹ yin nyin. Mo si tun ki nyin ti inawo ọmọ. Ọlọrun Ọba ko da ọmọ na si fun wa, ki o si se ni ọmọ alafubarika, lẹhinna, ko wa se ni ẹlẹmi gigun fun wa amin. Mo si tun ki iya ọmọ na pẹlu o. Ẹku ọjọ mẹta o.

Ohun ti o mu ki e ri owọ mi ni ibere ti Alfa J. S. Animashaun bere ninu iwe Irohin aludun ti 7/12/53. Mo si lẹ lati da Alfa wa na lohun ọrọ rẹ na ni kikun. Mo si wa ki Alfa wa na dada nitori Alfa na tẹle ọrọ Ọlọrun to wa ninu Kuran pe "FASIALU ALUSIKIRI NKUNTUN LATALAMUNỌ" Ọlọrun ni ko bere mimọ nigbati ẹnyin ko ba mọ. Nitori ko si ẹniti o mọ nkan tan. Iyẹn ni mo fi dupẹ lọwọ Alfa na ọ. Idahun ọrọ rẹ na ko si pọ rara.

Idahun:- Kosi ohun ti o fa ti awọn Ọba ilu fi nsọpe ki wọn maṣe ki irun ọdun ni ọjọ Jimọ. Ti nwọn ba si ki irun na ni ọjọ Jimọ yi, ko ṣe nkankan, Kuran ko sọ pe a ko gbọdọ kirun ọdun ni ọjọ Jimọ, bẹ si ni Hadih ko tako ọrọ yi, ọrọ aiye ni gbogbo iyẹn. Bi ilu kan ba ki irun ọdun ni ọjọ Jimọ iyẹn ko sọ pe ki Ọba ibẹ ku, aya fi ti ọjọ Ọba na ba ti pe.

Fun apẹrẹ ninu ọdun 1951 ni itunu awẹ, ọjọ Jimọ ni a ki irun ni Eko ati Ebute-Metta, o fẹrẹ jẹ gbogbo ilu ni papa, bẹ si ni ninu ọdun Ileya to kọja yi 1953, ọjọ Jimọ ni wọn ki irun ọdun. Ki lo se ti Ọba ilu na ko ṣe ku. Ọrọ igba-ohun asan-gbọ niyẹn (Superstition) ko si si ninu Iwe Ọlọrun kan. Ṣe ẹ wa ri Ọba ti o sọ pe ki wọn ma kirun ni ọjọ Jimọ ti Alfa yi wi, o jẹ ẹniti ko mọ mimọ rara ni. Ti o ba jẹ pe o mọ mimọ ni, ko ni sọpe ti awọn ba ki irun ọdun ni ọjọ Jimọ, on yio ku.

Nitorina ti ọdun ba bọ si Jimọ, ki ẹ ki o, kiṣe ewọ, bẹni ki si pa Ọba o, aya-fi eyi-ti ọjọ rẹ ba to o,

Abọ mi re o Alfa, ti o ba tun ku lati bere, ki o bere, o si ri awọn Alufa ti yio dahun rẹ o. Odigba ose na o.

Asalamu-alekun

Emi ni,

Alfa Rasheed A. Ola. Ayodeji

Ebute Metta.

si wa ti idahun na si dogba pẹlu ti Alufa Rasheed. A. Ola. Ayodeji ni Alufa Aminu P.O. Box 156 Zaria ati Alufa Idirisu Oyebanji P. O. Box 9 Zaria. Ẹ ku iṣẹ o. Ki Oluwa bukun Ọgbọn ati lakaye nyin o.

OLOTU.

AKIYESI: Awọn meji ti o tun fi idahun ibere Ọgbẹni Animaṣaun na ṣọwọ

## Awon Ero Oke-Okun Be Olotu wo

EKO - Ni Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni Ọgbẹni J. A. Arẹẹgbẹ, aṣoju Iwe Irohin Yoruba ni Ilu Ilorin se amọna awọn aṣoju Iwe Irohin Yoruba meji ti o de lati Oke-Okun wa si ọdọ Olotu Iwe Iro'hin Yoruba.

Awọn Aṣoju wa meji na ti o de lati Oke-Okun [Suhum Gold Coast] ni Ọgbẹni Solomon Fatokun ati Amos Adeoye. Ni ọjọ Kejila oṣu yi ni nwọn ba ọkọ ofurufu gunlẹ si Eko fun irin ajo lori iṣẹ owo wọn, bi nwọn ti de ni nwọn si se alabapade arakunrin wọn Ọgbẹni J. A. Arẹẹgbẹ ti o se amọna wọn wa si ile Iṣẹ Iwe Irohin Yoruba.

Nigbati nwọn de ọdọ Olotu ti Arẹẹgbẹ si mu wọn mọ Olotu ti nwọn si ki ara wọn pẹlu ẹyẹ tan ni nwọn ba bere si se aṣaro lori bi "Iwe IrohinYoruba" nṣ ti nlọ si ni Oke-Okun lọhun, lẹhin na ni Olotu ba mu wọn yika gbogbo idi ẹrọ-itẹwe titun ti Ẹgbẹ "Amalgamated Press of Nigeria Ltd" nlo fun itẹwe Irohin Yoruba ati "Daily Service".

Inu wọn si dun pupọ lati ri idagbasoke iṣẹ Irohin Yoruba, nwọn si ṣe ileri lati sọ fun awọn ara wọn l'Oke-Okun pe awọn Ẹrọ-itẹwe wa na to inkan ti enia le diide lati ilu okere wa wo.

Ni arọ ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejilinlogun ni awọn Ọgbẹni wa mejeji na si pada lọ si ẹnu iṣuJoko iṣẹ owo wọn ni Oke - Okun (Suhumu Gold Coast). Ọkọ arẹfọ o, a'o a dara, abọ asunwọn, Oluwa ko ni kọ atunri wa o.

### ODUN TITUN, OJA TITUN

Oruka Orire, Oruka Ifẹja, Oruka Asiki, Oruka Iyọnu Agbalagba, Turari Adura, Iwe Ipilẹsẹ Awa "Fẹ Ẹnikeji Rẹ Gẹgẹbi Ara Rẹ" ati ọgọnlọgọ ohun ajọ miran ti iwe yi kole gba. Kọwe fun Iwe Itaja titun ti o ṣẹṣẹ lade ọfẹ la tifun ni.

OLUWO.

36, King George Avenue, YABA. Nigeria.

# ISIN IRANTI BODE THOMAS



Aworan yi ni ti diẹ ninu awọn enia pataki pataki ti o wa si ibi Isin Iranti Bọde Thomas. Lati ọwọ osi :- Dọkita Akinọla Maja (Baba Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa), Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ (Olori Ẹgbẹ Action Group), Ọlọla S. L. Akintọla (Gbakeji Olori Ẹgbẹ Action Group), Dọkita Akanni Doherty (ọkan ninu aw n aṣiwaju Ẹgbẹ Action Group) ati ọpọlọpọ awọn enia miran nibẹ.



Aworan yi ni tito wọle Sọọsi nibi Isin Iranti Bọde Thomas. Alufa Ibitọla ti Ijọ African Salem Church EB ni o gbe ọpa iṣiwaju. Ẹni-ọwọ Bisọpu A. Abọyade-Cole, Oloye Okunlọwọ, aṣoju Alufa African Church Cathedral (Bethel) ni o tẹle Bisọpu na.

